# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. III. No. 110. SATURDAY, AUG. 23, 1924. Fourpence

**DURO THOMAS.**

35, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods,*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

26 AUG 1924

LAGOS

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Olokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumâdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; A ni nkan wọny fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ agbado, Ile, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Àjàrà (*Wine*), Awọn onjẹ ipanu, aşọ iş'ọşọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# John Walkden & Co. Ltd.

SUNDRIES DEPT.

MARINA, LAGOS.

## We recommend you to try our :—

"Elephant" Beer

Ginger Ale

Lemonade

Red Buffalo Gin

Black Prince Gin

Gilbeys Gin

Old Tom Gin

**QUALITY THE BEST.**

ALL PRICES REDUCED.

we hold a large stock of various Sundry Goods at cheap prices.

*Editor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Odun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

A-ŞORO FỌ BI EDE, EDE LO YỌ ẸNIKAN LANA.

A gbọ pe Ọgbẹni Ọmọ Ẹgba kan ti a şẹşẹ gba si'şẹ Gbedegbẹyọ (*Interpreter*) ni Kotu Jẹbu Ode, di ẹni ti a ni lati yọ kuro nipo na nitoripe ko gbede awọn ọmọ Alarẹ; bi Ijẹbu ba nro'jọ lọ, ti o ba si bu jẹ lojiji pe E şẹ! E şẹ (Eyini ni bẹkọ! bẹkọ) ara'le wa yi a si tumọ rẹ l'ede Ẹgba pe Hẹ rè! Hẹ rè (Eyini ni kiloşe) gbogbo Kotu a si bú s'ẹrin gbãgbãgbã: nitotọ ẹni m'eyi ko m'eyi, Alagbẹdẹ ko rọ'ke.

O TO GBE, ẸLẸRU GBE E!

Gomina Agba Sir Hugh Clifford yio gbe'ra ni'lu Oyinbo ni ọjọ kẹta oşu to mbọ lati pada s'ẹnu işẹ rẹ nibi; bẹ na si ni a gbọ pe Adele Ọba Sir Donald Cameron yio kuro nibi patapata lati lọ s'ẹnu işẹ rẹ titun bi Gomina Ilu *Tangayika* ni Ila Orun *Africa* niwọn ọjọ kẹwa oşu *October* ọdunni.

Ki Baba m'ọjọ ro fun t'ọtun t'osi, k' O si fun gbogbo awa na ni alafia ara, k' a ma ri "Dasi" Aşẹ.

DEBAYỌ, ỌMỌ ỌWA, IWỌ L'A FI Ş'AGBA, IWỌ LA FI ŞE E!

A ke si Ọgbẹni Debayọ Agbebi, Oludamọran ti Ile Itọju Ilu, ki o ma şai rẹ awọn enia to ngbe gẹrẹgẹrẹ Ita *Branco*, Ita Adu, ati Ita *Evans* l'ẹkun nipa fifi ọrọ ti titun adugbo wọnyi şe siwaju awọn Igbimọ rẹ; ati wa lẹnu ẹbẹ yi si awọn Olotu Ilu yi ki ş'aruwa; şugbọn sibẹsibẹ ibomiran ni nwọn nkọju işẹ wọn si, bẹ "gbogbo wa l'ọgún jọbi" eyini ni pe gbogbo wa lo nsanwo omi bakanna.

Ọgbẹni Debayọ, a f'ọrọ awọn ara Adugbo wọnyi kọ ẹ l'ọrun o, ma şai jigiri lati rẹ wọn l'ẹkun na.

LẸLẸ LO NFẸ, IYAWO DI TABA.

Iya-afin wa Samọta Ikẹ-Olorun Arowolo ti 3, *St. John Street* sin ọkan ninu awọn ọmọ rẹ obinrin Wulemọtu Agbekẹ awel'ọrun ẹlẹyinju-ẹgẹ ni iyawo fun Liamidi Tinubu ọmọ Ọgbẹni Saka Tinubu ti 57 *Kakawa Street* ni Alamisi *Thursday* ọsẹ yi. Rẹpẹtẹ ni Iya-afin Samọta fi'le pọn'ti to f'ọna ro'ka, ti awọn bẹrẹ nlọ ti nwọn mbọ lọdọ rẹ pẹlu ọwọ kurudu: a ko le şeşẹ sọ ti fa-nlala ti onjẹ pẹteri si ile baba ọkọ iyawo mọ.

A ki Ẹbi t'ọtun t'osi, Ẹ ku inawo, irufẹ bayi a ka'ri o.

IPADE ẸGBẸ TUNLUŞE.

Ipade gbogbo-gbõ Ẹgbẹ yi yio wa ni Ile Afari-Ogun l'Ẹhingbẹri ni agogo mẹrin aşalẹ oni. Ki ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ ki o pe.

---

ẸNYIN AWA ỌKỌ MỌTO ATI ẸNYIN ERO GBOGBO.

GBANGBA DẸKUN, KEDERE BẸ WO!

*Iwe si awọn Awa-Mọto ati gbogbo Ero inu ọkọ.*

Bi ẹ ba ti de eti Kereni ẹ ranti ki ẹ si jọ tẹ'sẹ duro diẹ ni ŞABU WAWO ti Ọgbẹni Ọmọşalewa Thomas ni Ebute-Metta, ti Ile-owo THE LAGOS STORES LTD, ti adape rẹ njẹ ANKURI MAGANI-DUNIYAN, Suru ni Ogun Aiye.

Epo Mọto (*Petrol*) nfẹ tan ni o, wa rira nibẹ, awọn Ero inu ọkọ Mọto tabi Railway fẹ lọ si Eko lati lọ ra ọja ni o, ẹ kọkọ ya si WAWO, ẹ

o ri awọn orişirişi ọja wọnyi nibẹ ni ọpọkuyọku :— PETROL, KEROSENE, GIN, Ọti Oyinbo orişirişi— "Ọti, Ọti, a si ma dun, bo lo mu mọ, a si ma dun—CORRUGATED IRON SHEETS, Panu Ikọle, CEMENT fifi kọ ile, Oluwa jẹ a ni ile lori o. Amin SALT, Iyọ ọbẹ, Ọbẹ ni ọmu agba, agba ti ko ni owo ọbẹ, a wa gari, SUGER, Iyọ Oyinbo, L. S. TOBACCO, FLOUR. Gbanjo o! Burẹdi, mejila tọrọ, mẹtala tọrọ ni mo ra ni'bi Oju Oto! STOCK-FISH, Ẹja Abọmafọ, RICE, Irẹsi Iganmu, Aşọ Agbanrọ, TERU-nla, ACCRA CLOTHS to jire fun YONKEE STYLE. &c. &c.

Bi o ba fẹ wọn ẹru rẹ sinu ọkọ *Railway* eyini ko şoro, ọgafa ni Ọgbẹni Ọmọşalewa yio fi Mọto ba nyin gbe lọ si *Station*, idi ọkọ ni Iddo tabi ni Ebute Mẹta. Ki a ma fa ọrọ gun lọ titi "Igbadun ati Faji ni lati lọ ra ọja rẹ l'ọdọ Ọgbẹni akikanju yi."

Bi a ti ngbọ nu u lẹnu awọn Ero ti o ti gbadun ọdọ rẹ ni ọja rira ati wiwọn s'ọkọ. Nwọn a si ma dọgbagba ẹrin ninu ọkọ bayi pe Akan o? Ho o Alao! Pagidari! Emi la tun nşe wahala lọ re ra ọja l'odidi Ẹhingbẹti lọhun şi? Ngo si ri ohun ti a nfẹ ti ko si ni Şabu Ọmọşalewa, gasikia le ni Ọmọşalewa ijọun ti Opopo-nla na ma şi ni? Elẹkeji, ko ba tan!

Emi ni tirẹ nitotọ
AYỌRINDE DUROJAIYE.

## THE BANKS' AFRICAN STAFF UNION.

A rather pleasant and happy evening was spent on Monday the 4th instant "Bank Holiday" at the Glover Memorial Hall when there was held by the members of the Banks' African Staff Union a grand Coversazione which no doubt proved to be the first of its kind in the history of the Bank in Lagos.

At 8 oclock p.m. the following gentlemen were already in evidence:—Messrs E. C. Hodgett, Manager Bank of British West Africa Ltd., J. F. W. Schofied joint Manager of Colonial Bank D. D. Gibb, Sub Manager B. B. W.A. Ltd., Mrs. D. D. Gibb, A. Conacher Accountant, Colonial Bank, Lawyer Rhodes, S. H. Bapdist, Jibowu, Franklin, Folarin, Mr. P. J. C. Thomas, Mr. Duro Thomas, Mr. J. A. Odufunade, Mrs. S. H. Pearse, etc. and with the twinkling of an eye the whole Hall had been packed full.

After several interesting Recitations and songs, the play, the Pantomine of "The Advantages of Banking' began. "The Manager of the Bank that Never Fails started with an introductory appeal a very attractive and convincing one urging every one who might hear the play to keep his or her savings at the Bank that Never Fails" where a depositor of £9 may draw £10 and still has £1 to his credit. "This appeal gave rise to much laughter from the audience, particularly those connected with the Banking's concerns" who though not doubting the ability of the General Manager of The Bank that Never Fails, yet cannot see the possibility of such a business in real life.

Another most miraculous sort of business that the Bank transacts is the issuing of its Letter of Credit which can be negotiated in the North, South, East, and West; above the sky, by aeroplane and by submarine under the bed of the sea—A wonder not found perhaps in wonderland.

The first scene of the first act portrays A mail Day in the Bank that never fails when clients are busy transacting various kinds of business such as, cashing cheques, depositing monies in the savings Department, receiving interests on Fixed Deposits, purchasing Draft, and making Telegraphic Transfers, while three gentlemen Messrs Riskitt, Dickinson, and Abdul would not avail themselves of these facilicties on account of the Bank's trifling charges.

The second scene describes the incident on the wharf when passeneers were embarking on the Liner "Zaria" sailing for Europe and other parts of the world quite unfortunately Mr. Riskitt's hand bag which, some people say, contains money exceeding £30,000,000 was smartly changed.

Dickinson the second gentleman of the three who ignored the Bank's facility also dropped packets of Currency Notes as he was climbing up the ships gangway. Mr, Dickinson told only a friend and that quite secretly that he was bound for Jamaica.

In the second act appeared one Mr. Felix George attempting to move the specie required by his firm at their up-country branches when quite unhappily, he and the labourers were encountered by highwaymen who injured them and went away with the money. Next came Mr. Abdul the third of those who refused to keep their money at the "Bank that Never Fails" Abdul's house was on fire, while Fire Brigade and Boys Scouts hurried to the scene to put down the fire.

In spite of all efforts to save every thing for Abdul, £5000 worth of currency Notes was, to his sorrow reported as having been destroyed by the fire.

The play ended at 10.30 p.m. when dance commenced until the small hours of the morning. The first dance was by the Bank Staff only and at this stage the absence of Hon. W. F. Becker was regrettably felt. The function was a decided success.

Hearty congratulations to the members of the Union.

God save the King.

HASSAN HASSIEN

## OŞUPA KO LE JA MỌ ORUN FISILẸ! FI LAKA LAKA JU SILẸ!!

[ Lati ọwọ GBARUKU. ]

Ni alẹ ọjọ Alaruba ọsẹ to kọja (14/8/24) ni dede agogo meje abọ ni Orun pẹlu Oşupa bọ si ọkankan ara wọn, eyiti awọn enia-wa npe ni Oşupa pẹlu Orun nja. Eyi kọ ni akọkọ ja Orun pẹlu Oşupa ni'lẹ yi, şugbọn ohun to jẹ iyalẹnu fun wa ni pe bi a ti nsọ pe ilaju ti de si ilu Eko to yi, ti a si sọ pe awọn Imale ti a ti npe ni alagbada ri ti şẹ ndi oni *Coat and Trousers* to yi sibẹ-sibẹ oju dudu koi ti kuro larin wọn.

Ohun ti a kọkọ ma ri ni alẹ ọjọ ti a nwi yi ni ẹgba-gbeje awọn ọmọ wẹwẹwẹ ti nwọn npariwo kakiri ilu ti nwọn si nkọ orin ko jọ aro ko jọ yẹyẹ bayi :—

Oşupa ko le ja mọ,
Orun fisilẹ,
Onişẹnla!

Awọn kan ngbe bayi pe :—

Fi lakalaka! Ju u lẹ ẹ!
Fi lakalaka! Ju u lẹ ẹ!

Eyi ko ya wa lẹnu nitoripe ere ọmọde l'a pe şugbọn ni nkan agogo mẹjọ abọ de mẹsan a ri pe bi ere bi ere alabọrun d'ẹwu nipa pe aimọye awọn Alufa oni lawani banti-banti pẹlu ọpa lọwọ bẹrẹ si tu jade, nwọn si nkọrin lohun keu kakiri.

Nigbati a wa'di rẹ si ọtun wa si osi, a tun gbọ pe otitọ ni awọn onilawani wọnyi gbagbọ pe Orun pẹlu Oşupa nja, ati pe ti nwọn ko ba tuwọ ija, aiye yio parẹ.

Ọrọ re o, ẹnyin janma ọkawe wa! njẹ ki li o da'di ija, a ko ri ẹnikẹni lati sọ fun wa afi oniyẹyẹ kan to ni Iya-Aladalu kan lo da'ja silẹ fun wọn. O ni Orun ran Oşupa ni Adalu ni owurọ nigbati o dari de l'alẹ, o ri pe Oşupa ko ranti gba epo si i!

Ju gbogbo rẹ lọ, ẹ jẹ ki a bere pe tani ran awọn Alufa nwọyi ni işẹ ti nwọn njẹ? Ohun ti Alalukurani wi ni pe Oşupa pẹlu Orun ko le rin pade arawọn.

Ngbọ? Iwọ Alufa oni lawani nla ti o ko jẹ ki gbogbo ilu ri eti gbọran ni alẹ ọjọ t'a nwi yi, ti o ko jẹ ki aladugbo sun nipa keu Aramukandu to nke kiri ilu—ti ẹ ti jẹ? Apa ibo ni Alukurani fi kọ ẹ pe Ọşupa pẹlu Orun nja?

Ẹwẹ, a gbọ ti awọn ti ọrọ ki iye, ewo ni ti awọn ọdọmọde ti a ro pe diẹ ninu wọn ni mimọ ti a si ro pe nwọn ko le şai ti pade iwe ti a npe ni *Geography*. *Geography* fi kọ ni gbangba pe Orun pẹlu Oşupa ko sunmọ ara wọn arara de'bi ti nwọn fi le şe gbolohun asọ, ki a ma şẹşẹ sọrọ gidigbo.

Lalai si pe a nşe ete l'ẹşọ, ẹgbẹgbẹrun-ọna-ẹgbẹrun-ọna-mẹtaleladọrun (93,000,000) ni busọ ti Orun fi jina si Aiye ti a wa yi.

Ẹgbẹgbẹrun-ọna-ojulugba (240,000) ni busọ ti Oşupa fi jina si aiye yi. O wa han gbangba pe ẹgbẹgbẹrun-ọna-ẹgbẹrun-mejileladọrun-ole-ẹgbẹgbẹrun-ọna-ojidilẹgbẹrin (92,760,000) ni busọ t'owa l'arin Orun pẹlu Oşupa ti awọn ara'le-wa sọ pe nwọn yọ kunmọ nwọn nlu'ra wọn. Bawo ni eleyi ti şe le şeşe? Bi Orun yin ibọn ti ọta ibọn na kan iyẹ mọ apa ti o nfo bi ẹiyẹ ko le de ọdọ Oşupa.

Ti ẹ ba bere lọwọ awọn ogunna-gbongbo ninu iwe, nwọn yio sọ pe bẹ ni ọrọ na ri.

Bi a ba wi taiwi awọn kan a ni kini njẹ *Geography?* Nwọn a ni itan Oyinbo ni. Şugbọn bi o ti jẹ itan na to yi, ni awọn Oyinbo fi nfi ori ọkọ wọn sọ alagbalugbu omi okun lati ilu wọn ni *Southampton* tabi *Liverpool* wa si Eko. E jọ ki awọn ajẹ'ja nwọnyi gbe ọkọ Ejinrin kan tabi ti Ganwun ki Oyinbo gbe ti nwọn ki nwọn d'ori kọ ilu Saro nitosi nibi. Nigbati o ba ma fi di ọjọ keji ti ẹ ko ba şa ọkọ Ganwun yi ni etikun Langbasa ki ẹ gba lọwọ emi *Gbaruku!*

Nitorina Oşupa pẹlu Orun nja ewọ Aiye ni, Ẹkọ ki kọ ila, ka ko ila kuro l'ẹkọ!!!

GBARUKU.

---

## FROM THE EDITOR'S SANCTUM.

### "DRUNKEN" INSPECTOR, BEWARE!

It is reported that a certain Inspector, (whether of Police or of Nuisance, the deponent sayeth not:) is always in the habit of making an ass of himself—reader, pardon the term, the occasion justifies it—by going out of his way in disturbing peaceful citizens whenever he is anything but sober: the practice, it is said, was brought into bold relief lately when he disturbed a harmless masquerader who was engaged in dancing to the delectation of the people in a certain vicinity. If this be true, we would counsel the Inspector to reflect on the truth enshrined in these lines :—

"Man, vain man,
Clothed with a little brief authority,
Plays such fantastic tricks,
Before High Heaeven,
As make the Angels weep.

### PITY THE POOR CLERK.!!!

We learn that a Petition from some leading sections of the mercantile African *employes* is on the rounds to the local Head of the conbine firms, for "a living wage" and adequated commissions. It is hoped a *sympathetic* ear will be lent to this Memorial.

### AFRICAN STAFF AT "HOME."

The African Staff of The Nigerian Secretariat are "At Home" this afternoon in honour of the opening of their new Tennis Court by His Excellency The Acting Governor and Lady Cameron. "Congrat," is the word.

---

## Thanks for Sympathy.

Mrs. Angelina Labinjo, of 28, Luther Street, and Madam Damiana Silva of 39, Glover Street, Lagos, for themselves and on behalf of their families hereby return sincere thanks to all those who by their personal calls, letters, telegrams and otherwise have sympathised with them on the occasion of the Home-call of their dear Aunt and Mother PATIENCE TAIWO OGUNBIYI at her residence 66, Obadina Street, on Sunday the 10th instant.

---

## A DUPẸ OJỌ.

Iya-afin Angelina Labinjọ ti No. 28, *Luther Street*, (l'eti Mọşalaşi Olosun) ati Damiana Silva ti No. 39, *Glover Street*, pẹlu awọn ẹbi wọn dupẹ gidigidi lọwọ gbogbo awọn ọrẹ, ojulumọ ati awọn ẹlomiran ti nwọn wa ba wọn kẹdun ọfọ to şẹ wọn nipa Anti wọn PATIENE TAIWO OGUNBIYI to lọ sinmi lọdọ Baba l'Oke, ni *Sunday* ọjọ kẹwa oşu yi

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, August 23, 1924.

### "ILABIRU" TO BA Ọ NI'LẸ YI TI RẸSIN, IWỌ SA JOKO S'ẸNU MI!!!

Kodẽde ti a fi kọ irufẹ ọrọ bayi s'oke Iwe pataki wa ti ọsẹ yi, nitori nigbati a wo iwaju wo ẹhin ni igboro ilẹ yi, ohun ti pupọ ninu wa ma nsaba lati gba'rajọ ṣe ju ni ohun ti yio rẹ ọmọ ẹnikeji wa si'lẹ: ki a fun nyin ni apẹrẹ kan, bi awọn "Akẹran" ba ṣeṣi mu oloruko kan ni Ilu eyiti a nwi yi ti pẹ, irohin mimu na yio ti tan ka origun mẹrẹrin ilu ko, ki o toto aṣalẹ, nwọn ti gbọ jakejado *Nigeria* pe nwọn ra Lagbaja mu; nigbana ni iwọ yio ma gbọ ọkan ko jọ'kan ọrọ iṣọnu bayi, "ọwọ tẹ ara'le rẹ wayi, ng o wi fun ẹ?" "Ṣio! galegale rẹ pọju" "ko ṣe bi o ti mọ," "obinrin to nkowo fun ko ni'ye," "Afojudi rẹ nkọ? O to ti ẹgun kekere to nki baba rẹ ni ọku" ati irufẹ maṣaṣi ọrọ bawọnni; bayi ni awọn enia wọnyi ma nj'oye "ik ko dudu ti ko gbọ ti ara rẹ to ngbọ t'ẹni-ẹlẹni;" ṣugbọn ta la ma yẹwo ti a ko ni ba nkan laifi ni sakani rẹ? Aro ẹnit'o ṣa yọ la nrẹ; bẹna ni, olukuluku lo nj'oye orule b'aja mọ'lẹ, aṣọ bo'ṣe idi. Ipa ni a le fi ri idamẹta enia ki nwọn tilẹ daro irufẹ ẹni bẹ. Iwa yi tubọ npeleke larin wa nibi tobẹ ti ominu fi nkọ ni pe sibẹsibẹ dabi ẹnipe pupọ ko ti mọ ohun ti awọn nṣe: ẹ'ẹ awo ni ẹtẹ ọgbẹri, owe Yoruba ni; ko si ohun meji ti a nfẹ loju mejeji nisisinyi ju Iwa Ifẹ ati Iso'wọpọ fun iṣẹ rere gbogbo ti yio ma mu ilu ati Iran wa tubọ ma tẹ atẹsiwaju lọ.

Ẹnyin Ẹ tilẹ wo bi ọgi ti parada to d'ẹkọ to, ninu iyipada tamutamu ti o farahan gedegbe lara awọn Oyinbo ti a npe ni "Kọ'ra" (*Syrians*) ti nwọn ti igbo meje ati ọdan meje wa si ilẹ yi l'eni tere eji tere, ti nwọn si fi Ebute Ẹhingbẹti ṣe ile nibiti nwọn ngbe nta ilẹkẹ iyun wọn nigbana: awa papa gbọnju mọ pupọ ti nwọn ko ni isọ a-mbọsi-bọsi Ṣabu tabi ile ti nwọn le ko iyun wọn wọnyi si nigbana, bikoṣepe ki nwọn na wọn s'ori apoti pagunpagun bi meji mẹta ti a to pọ, fun awọn ero onibara wọn.

Nigba pupọ ẹwẹ, nwọn a ma kiri ọja yi kakiri igboro Ilu nibi, nwọn a sọ awọn iyun na s'ejika pẹlu irahun ti o dabi ti ẹniti ebi ti fẹrẹ yọ loju, Ẹ sã gbọ ohun irahun wọn igbani na; kọ-ọ-ọ-ọ rá-à-à-á! kọ-ọ-ọ-ọ rá-à-à-á!! kọ-ọ-ọ-ọ rá-à-à-á!!! bayi ni aṣa awọn ajeji yi ni igboro ilẹ yi niwọn ọgbọn ọdun sẹhin.

Ṣugbọn loni nkọ? Awọn Oyinbo kanna yi ti kuro ni ẹniti o nfi ara gba otutu ti ile wọn lailai-ani Ẹhingbẹti, ki nwọn to le ribi ta panduku wọn, nwọn si ti di ẹniti o nra ile kun ile, ti nwọn nkọ aṣẹ kun aṣẹ, ti nwọn si nra oko kun oko. Ẹ lọ si Ereko, ẹ o ri ọwọ nwọn nibẹ, ẹ lọ si Ita Agarawu, ẹ o ri ọwọ wọn nibẹ, ẹ lọ si Ẹhin Ọgba, ẹ o ri ọwọ wọn nibẹ. A ko tilẹ ha gbọ ni sã kan pe ninu wọn jẹ kumoyo tan, o si npete lati ra gbogbo Ereko "pa" bi a ba fun on l'aye rẹ? Tabi otitọ ha ni ọkan tabi meji ninu wọn bẹrẹ si nhan awọn Alapata wa le-nmọ nipa pe ki nwọn fi owo lu awọn malu ti awọn ara wa nṣẹṣẹ ngiri ra ni Sango pa patapata nipa rira wọn ti *Wagon* ti *Wagon*? A tilẹ gbọ pe diẹ ninu nwọn tilẹ bọ si owo ekurọ rira nisinsinyi; bi ere-ẹgin-sisa ba si de, iru ni wọn, nwọn ko ni wọn nibẹ.

A ko sọ gbogbo evi lati ṣe ilara wọn, tabi lati fi yọ ṣuti si wọn, ṣugbọn a sọ fun itagiri awọn ara wa nibi ati nibomiran pe awọn ti awọn ẹlomiran ti le ma pe ni "Ilabiru" ninu awọn ajeji to wa si'lẹ yi ndi Araba, ti apa ọmọde ko ka mọ l'ode oni.

Ohun ti a ri pupọ inu wa si, ko ju ṣiṣe fãri ete lọ, "yanmu-yanmu nge fuja lai-lapa:" ṣiọ! bẹni a bi ni l'Eko ko d'owo. Ogo ni ọkan ninu awọn Alarandun wa nkọrin bayi pe :—

"Ọmọ Onile nsun ẹsẹ bi Ewurẹ
Ajeji nsun Pẹtẹsi."

Ti a ko ba ti bẹrẹ si ronu ohun ti a ti nsọ bọ yi, njẹ asiko to lati jigiri niyen fun

is'ọwọpọ ṣe iṣẹ owo tabi ohun rere miran gbogbo; ki a ye joko s'ẹnu nmi, ki a tilẹ tun bi ara wa lere, o di "Kọ̃ra" melo la ri ti o ndi *Application* (Iwe Iwaṣẹ) mọ aiya kiri wa iṣẹ lọdọ Ọba tabi ti Oyinbo onişowo? Awa papa koiti ri ọkan ki o ṣe bẹ ri, kàka bẹ, nwọn a s'ọwọpọ larin ara wọn lati da ina òwo ti awọn pãpã silẹ.

Ẹnyin ọmọ iya wa, Ẹ ko ha ri idi Abajọ wọn bi? Awọn Oyinbo lo ma npa l'owe pe:—*what man has done, man can do.* eyini ni pe ohun ti ẹnikan ba ti ṣe ri, ẹlomiran si tun le ṣe bakanna ti ko pada. (Ajulọ ko pin s'ọdọ ẹnikan).

Nitorina ẹnyin ara wa, ẹ maṣai da gbolohun ọrọ diẹ ti a sọ yi ro, ko yẹ ki a ma fi gbogbo ọjọ wa "jagun bi ẹru" Owe ti ẹnyin agbalagba o!!!

Lãkaye lo ju
K'a ṣiṣẹ bi ẹru ko da nkan.

---

## IKU DOKITA BECKLEY KO Ş'ẸHIN ỌLỌRUN!

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Şi Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

A-gbọ-ju-'gba-nu ni iku Dr. Emanuel Olubomi Beckley, M.B., ti o ṣẹlẹ ni ile rẹ, ni owurọ Satide ijẹdogun, *August 9th, 1924.*

O dabi ẹni wipe enia ko ku şiwaju rẹ ri ni Ita Balogun, bi ẹkun on aro ti pọ to. Ọmọde uda omi l'oju wuru, şibaşibo mu agbalagba bi agutan, obirin ngbe ara ṣanlẹ bi igbati Rachael nsọkun awọn ọmọ rẹ, ti ko gb'ipẹ, nitoriti nwọn ko si.

A bi Dr. Beckley ni Apọngbọn *Street*, Olowogbowo, ni oşu *September, 1881*, lati ọwọ baba rẹ, Ọgbẹni Thomas Elliot Beckley ati Jane iyawo rẹ. Enia pataki ni awọn Obi rẹ l'ọtun-l'osi

Daddy Beckley jẹ ọkan ninu awọn Ẹgba ti ọtẹ ogun tẹ lọ si Saro, ilu ajeji, ni ọdun gbọrọ; o si jẹ ọkan ninu awọn ti a da silẹ ni ominira lẹhinna, ti o si pada wa ile.

Awọn Daddy ẹlẹgbẹ rẹ ni Henry Robbin olowo Ake, C. B. Moore, P. P. Martins, Ajọbọ Coker, Ọṣọba George olowosokedilẹ, S. J. Peters ati awọn jakanjakan miran.

Akọni enia ati Onişowo ni Daddy Beckley nṣe.

L'aika ọmọ ti o fi ọwọ ara rẹ sin, awọn ti o fi silẹ l'aye lẹhin iku rẹ to mẹdọgbọn. Dawodu wọn ti awa mọ ni Ologbe, Ọgbẹni Joseph O. Beckley ti Ojokoro *Farm*, Agege, nibiti o kọ Şọşi nla kan si, ti on papa si ṣe alaisi li ọdun ti o kọja. Ọlọrun ko fi ọrun kẹ ẹ.

Gẹgẹ bi ọpọlọpọ Ẹgba igbani ati ti isisiyi, igbagbọ Daddy Beckley ko gbona de ibi olobirin kanşoşo. O fẹ, o tun fẹ; şugbọn, alarede "*For better, for worse*" ni. O gbe Jane ọmọ Daddy olowo kan "Tamantijo" Thomas Joe ni iyawo, iyawo yi si bi ọmọ mẹrin—ọkunrin meji, obirin meji. Sam, Eman, Jane ati Matilda.

Ọgbẹni I. B. Williams kanna ti Opopo-nla, *Broad Street*, Lagos, li o gbe Jane akọbi ni iyawo ni ọdun 1887, Ọgbẹni Nash. H. Williams, *Barrister-at-Law* li o si ṣe *Bestman* rẹ

Gomina ti o wa li Eko nigbana, His Excellency, Captain C. A. Moloney, C.M.G., lọ si ibi iyawo na, on li o si sọrọ nipa iyawo ati ọkọ rẹ (*Toast of the Bride and Bride-groom.*)

Ọjọ pẹ, igbagbe ṣẹ nde diẹdiẹ. Şugbọn awọn ogun (20) ti a ranti wipe nwọn şe Ọmọ-iyawo (*Bridesmaids*) li ọjọ na ni:—Ọmọge Charlotte ati Maria Blaize, Sabina Thomas, Bernice Johnson, Fanny Davies, Emily Davies, Beatrice Williams, Agnes Johnson, Phebean Williams, Ada King, A. Bucknor, A. Leigh, Laura Lake, Bernice Bailey, Jane Cowan, Adel Willoughby, Felicia ati Etta Benjamin, Mabel George ati Adel Williams.

Diẹ ninu awọn enia pataki ti a ri nibi iyawo yi ni:—Gomina pẹlu *Private Secretary* rẹ, Geo. Stallard, Esq., L.L.B., *Barrister-at-Law*, The Honourable Oliver Smith, M.A., *Barrister-at-Law*, Alufa S. Pearse ati C. B. Macauley, Alufa I. Oluwọle ati iyawo rẹ, M. J. Luke ati iyawo rẹ, J. A. Payne, F.R.G.S., F.R.C.I. J. S. Williams, Benjamin Dawodu, T. Augustus. Lord Bright, J. S. Bucknor ati iyawo rẹ, J. B. Benjamin ati iyawo rẹ, Adolphus Pratt ati iyawo rẹ, W. R. Harding, John O. George, J. A. Savage, D. Murray, A. C. Willoughby, R. B. Blaize, Z. A. Williams, C. Ungebauer ati awọn jakanjakan miran pẹlu. O di ọdun mẹtadi-logoji loni, şugbọn li oju wa, o dabi ana.

*Dispenser* Mason Ologbe, li o gbe Matilda ni iyawo; şugbọn igba ko lọ bi orere, Jane ku, Matilda fi ilẹ bora, Sammy, bakanna, lẹhinna ni aburo wọn patapata Eman Ologbe, ti a nsọrọ rẹ yi.

Eman jẹ ọmọ igbalẹrọ lati kekere, ko nşe apọn, ori rẹ ya si Iwe mimọ tabi Ẹkọ, o si ni itẹriba pupọ. Lọya Şapara Williams ati Bishop Oluwọle ni onigbọwọ (*Sponsors*) rẹ.

Lẹhin ti awọn Obi rẹ kọ ọ ni ẹkọ diẹ ni Ile-iwe *Wilton House School* ti Jane ati Matilda, awọn ẹgbọn rẹ mejeji da silẹ ni Olowogbowo ni ọdun kọkandi-logoji ọhun, 1885; nwọn fi Eman ranşẹ si şukuru giga lati kọ ẹkọ kun ẹkọ, ati imọ kun imọ. Warawere nibẹ, "o tan Keu, o yọ Wala.

O lọ si Saro lẹhinna fun a-kọ-mọ ẹkọ; o gba oye B.A. ti *University of Durham* ni Ilu Oyinbo, o si bẹrẹ si kọ iṣẹ Dokita nibẹ. Lẹhinna, o gba oye janrẹrẹ:—M.A., M.B., CH.B., L.R.C.P., L.R.C.S., L.F.P., and S.D.T.M., D.PH.

Daddy Beckley pẹlu alarede rẹ, iya Eman ti ku ṣiwaju akoko yi, ṣugbọn owo ti nwọn fi silẹ fun u lati pari ẹkọ rẹ wa labẹ abo ati itọju Ọlọla J. J. Thomas ologbe.

Dr. Beckley wọ Ẹgbẹ *Freemason* ni *Scotland*, Ilu Oyinbo, alẹ ọjọ kanna ni a si mu on pẹlu Dr. Sẹsi Akapo ati Dr. B. J. Ọdunbaku Hoare mọ awo nibẹ. Lẹhin ti Dr. Emanuel Olubomi Beckley de si Eko lati Ilu Oyinbo ni ọdun kọkanla, 1913, o lọ si Ilu Aganyin (*Gold Coast*) lọ ṣe iṣẹ.

Iṣẹ Dokita rẹ da a loju tobẹ gẹ, ti ko fi gba a ni asiko gigun rara ki o to di korikosun ọpọlọpọ alaisan ti o wa ni ilu na. Okiki rẹ si kan kakiri agbegbe Ilu Aganyin, Elmina, Saltpond ati ibomiran pẹlu ti awọn ẹlomiran fẹrẹ le gbagbọ wipe Dr. Beckley le ji oku dide!

O kọ *Hospital* nla tabi Ile-alarun si *Palm House, Cape Coast*, orişirişi egbogi li o wa nibẹ. Okiki kekere kọ ni Dr. Beckley ati *Hospital* rẹ ni ni Ilu Aganyin, ani okiki ti o gbe *His Excellency* Sir Hugh Clifford, Gomina ibẹ li akoko na lọ sibẹ pẹlu Dr. O'Hara May, *Senior Medical Officer of Health* lati fi onjẹ oju fun oju, ti o si fi ọwọ si Iwe-ero (*Visitors Book*) ti *Hospital* na, ki o to kuro nibẹ li ọjọ ti a nrobin rẹ yi.

Ni ọdun kẹjọ, 1916, o sọ ọpọlọpọ asọye (*Series of Lectures*) fun awọn ọmọ Ile-iwe *S.P.G's Grammar School* ati *Infantsipim School, Assemble Hall, Cape Coast* lori *Hygiene* ati *Physiology*. Lẹhinna, o ni ki Oyinbo Dr. O'Hara May dan wọn wo, o si fi owo ara rẹ ra Ẹbun (*Prizes*) ti o pin fun awọn ọmọ ti o ṣe daradara.

Nkan nlọ dede fun Dr. Beckley li akoko yi. Nkan ndun yungba-yungba bi ọsan agbalumọ. Bi o de ibi, orukọ Dr. Beckley; ọhun, bakanna.

Inu-rere nkọ? Pataki ero rẹ kini ni idide alaisan; lẹhinna, Owo-iṣẹ ni iwọntunwọnsi—l'aika ogunlọgọ enia ti o ṣiṣẹ fun l'ọfẹ—ẹlomiran, nitori aini wọn, ẹlomiran, nitori nwọn jẹ ojulumọ rẹ.

Bayi ni Dr. Beckley nṣe ni Ilu Aganyin, nibiti o wa titi ailera fi ṣe idina nla fun u. Agutan kan li o gbe e ṣubu nibẹ lori Bọnjọn oni-pupu, (*Motor-cycle*) ni ọdun keje, *November, 1917*; Egungun-iha rẹ ṣẹ.

Lẹhin itọju pupọ lọhun, o wa'le, o lọ si *Hospital* Dr. Gray ni Onikan. Nibẹ ni o gbe fun igba diẹ, lẹhinna, o lọ si ọdọ ẹgbọn rẹ ologbe, Joseph Beckley ni Agege, lẹhinna, o gbe pọ pẹlu Alufa T. A. J. Ogunbiyi, ẹniti o ṣe ajo rẹ pupọ ni *Parsonage* Ebute-Ero, o si jori amodi nla yi.

Boya eyi li o jẹ ki Ilu Aganyin su u patapata lẹhinna, awa ko mọ; ṣugbọn, o fi ọpọlọpọ ẹru rẹ silẹ nibẹ ati *Hospital* rẹ pẹlu egbogi pupọ. O mu ọna Ilu Saro pọn. Nibẹ pẹlu, o ni *Hospital* kan, "*Jane's Nursing Home*" ni *Oxford Street*. O nri iṣẹ ṣe nibẹ, ti-rẹ ni ero nwọ lọdọ rẹ; ọpọlọpọ alailera li o mu l'ara da, pẹlu ọdọmọkunrin Dokita Saro kan ti o ṣẹṣẹ de lati Ilu Oyinbo nigbana, ti o si ko agbako aisan ti o gb'ọwọ.

Lẹhin eyi, Dr. Beckley fi Saro silẹ, o wa si Eko. O kọ iwe fun aye tabi ipo Igbakeji Dokita Olutọju Ilu, (*Assistant Medical Officer of Health*) ti o ṣi silẹ nigbana.

Nwọn ni Dokita ti o gba oye D.P.H.—*Diploma in Public Health*, ni nwọn fẹ fun ipo na; ṣugbọn kekere patapata ni oye yi jẹ ninu awọn rafanda oye ti Dr. Beckley gba; sibẹsibẹ, awọn alatako ta ko o nibẹ, iṣẹ na ko si bọ si i lọwọ.

Dokita Enia Dudu kan ni Ilu Oyinbo ti o ṣẹṣẹ gba Oye M.B., CH.B. ati idaji ninu Oye D.P.H. tun kọ iwe fun ipo kanna yi, nwọn si f'esi wipe nwọn ko le gba a si ibi iṣẹ na, ayaṣebi o gba Oye D.P.H. tan. Oye ti Dokita Beckley gba, ti a si fi iṣẹ na du u.

Ọpọlọpọ Dokita miran ni a tun gbọ pe o kọ iwe bere fun ipo yi, ṣugbọn, pabo ni!

Nikẹhin, Dr. Isaac Ladipọ Oluwọle, ọmọ Biṣọpu d'aba wipe ki a fi on si ipo na, l'aigba Oye D.P.H. ti nwọn nfẹ, nwọn si jẹ ọhẹn, nwọn gba a; ṣugbọn o ni lati lọ si Ilu Oyinbo lati tubọ kọ iṣẹ Dokita si i, ki o to le gba Oye na.

Ilu ni yio san owo Ọkọ alọ, ati abọ rẹ, Ilu ni yio san owo oṣoṣu fun u ni Ilu Oyinbo laiṣe iṣẹ kọbọ kan fun Ilu, ṣugbọn lẹhin ti o ba ṣe oṣu mẹrin tabi mẹfa lọhun, ti o si yege Idanwo rẹ ti o gba Oye D.P.H. nigbana ni a o fun u ni ipo ti o kọ iwe fun, bi bẹkọ, ti o ba bolẹ ninu Idanwo rẹ, yio san gbogbo owo ti Ilu na le e lori pada laisi ele, (*Interest*) a o si gba ipo iṣẹ *Assistant Medical Officer of Health* lọwọ rẹ.

O nlọ ni oṣu ti o mbọ.

Anfani nla ni eyi jẹ fun Dokita ọmọde yi, adura wa si ni pe ki o le lo anfani na daradara fun ire ilu, fun ire ara rẹ ati fun igbeleke ogo Ọlọrun.

Lati igbati awọn Munisipa ti fi Dr. Beckley, ẹniti o gba oye D.P.H. silẹ laigba, ti nwọn si ṣe eyiti o wu wọn, mpa fi fun ẹniti ko gba oye na laye, ni Dr. Beckley ti tubọ tẹ ipa mọ iṣẹ pẹlu aisimi, aibaye, l'ọsan, l'oru.

Laipẹ, o di ọrẹ awọn aboyun, iyekan awọn abiamọ, to nrọbi, ati olufẹ awọn olokunrun.

Bi o ba ni iwa to "buru pupọ julọ" lọna iṣẹ rẹ, iwa na ni eyi pe, nigba pupọ to ba ti ṣe iṣẹ tan, ko nranti bere owo iṣẹ re, "kaka bẹ, o tilẹ nfun alaini ati talaka alaisan rẹ miran ni owo onjẹ lọsọsẹ.

Iru enia bayi ni awa mọ Dr. Beckley si larin ẹbi, larin ẹgbẹ, larin ọgba. A ko pe e ni Mọleka, nitori gẹgẹ bi ẹda, o ni alebu tirẹ, ani alebu totọ, totọ.

Fa'ri-fa'ri ko le ṣe onigbajamọ ara rẹ, aisan kọlu Dr. Beckley, o dubulẹ ni alẹ ọjọ *Monday, August 4, 1924*. Ere ni, awada ni; iku nkan

ilẹkun ile rẹ ni ita Balogun ko, ko, ko, ko, ṣugbọn Dr. Magnus Macaulay to ntọju rẹ ko ṣ'ilẹkun.

Dr. Macaulay nlọ, o nbọ, o nsure sihin, sure sọhun; egbogi atata, egbogi to jire wo lo ku ti ko lo sibẹ? Ko si. Bẹ gẹgẹ ni M. A. Beckley ọkan ninu aburo Dr. Beckley nṣe ajo totọ totọ.

Nigbati Dr. Macauley ndu Dr. Beckley mọ Iku lọwọ bayi, Iku gbe kumọ o di adugbo miran ariwo nta ge e—ibosi Iku. Iku tun gbe'ra o di ọna Ita Balogun ni ọjọ *Thursday*, o tun gun Pẹtẹsi Dr. Beckley o tun bẹrẹ si kan ilẹkun ile rẹ, Dr. Macaulay tiri si oju ọna, nigbati arẹ nde ni irọlẹ ọjọ *Friday*, o daba lati pe Dr. Faderin keji ara rẹ, Dr. Beckley si jọhẹn si imọran yi. Ṣugbọn ni idaji owurọ Satide ọsẹ kanna, Iku wọ'le bi ẹfufu lile, Iku wọ'le bi ọlọṣa l'oru, o si ji oku Dr. Emanuel Olubomi Beckley gbe salọ!* O ṣe, o pọ, o di gbere, o di arin-na ko, o d'oju ala!!!

A ti sọ diẹ nipa ologbe Dr. Beckley, diẹ nipa ajo ati itara Dr. Macaulay, awa fẹ fi abọ sori Dr. I. Ladipọ Oluwọle.

Anu ṣe wa pe ti a ba ni ki a bẹ'gi, ao bẹ enia Oju ẹni ọwọ Bisopu Oluwọle ati ẹni Ọlọrun iyawo rẹ ati Edmund Johnson ọrẹ wa ti wa pupọ; bi ki. ṣe bẹ ẹ, a ba ṣe Ladipọ ọmọ wọn bi ọṣẹ ṣ'oju fun galigali rẹ nidi oku Dr. Beckley, a ba si gba a ni imọran pe, to ba fẹ, ko lọ sin ibiti "ọpa bata" wa ba ba a.

· Nitori ailera Oko Awo ti a dupẹ pe o nlọ si okun igbagbe nisisinyi, Dokita olutọju Ilu kede pe ki a gbe ogun si ekute, ki a yẹ'ra fun aja, ki a yago fun ologbo. ki a si jẹ ki ile wa mọ toto. O tun fi wa ṣe ọlọpa inu ara wa, lati ṣ'ofofo ẹnikẹni to ba dubulẹ aisan lojiji, ati ẹniti amodi rẹ mu ifoya dani, nitoripe, o le jẹ aluba Oko Awo lo nba oluwarẹ ja.

Laisi ani-ani, gbogbo ikede ati ikilọ nwọnyi, fun ire wa ni.

Ṣugbọn niwọn igbati o jẹ pe ọga nta, ọga nra ni Dokita larin ara wọn, a tanma pe awọn ọgbẹri ni ikilọ Dr. Wm. S. Clarke nbawi ju awọn Dokita lọ. Dokita ki Dokita to ntọju alaisan lai mọ ohun to nṣe e, to ṣẹṣẹ nduro ki Dokita miran sọ irufẹ amodi to nṣe fun on, kuro ni Dokita atata, o di ope aperun, bẹni ope aperun ko si ninu Dokita to tan keu to si yọ wala ni Ilu Oy nbo, ko to wa'le, ka tilẹ wipe Dokita na ko mọ egbogi aiperi.

Niwọn igbati arun ekute *Bubonic plague* ba se'de ni Oko Awo bi oro, iṣẹ olukuluku wa ni lati sa gbogbo agbara ati ipa wa titi ao fi ri ẹhin aluba na, papa nipa ṣiṣe ofofo gbogbo aisan ati iku ojiji to ba mu iyemeji dani, gẹgẹ bi ilana Dokita olutọju Ilu.

Sibẹsibẹ, ẹnikẹni to ba ṣe ofofo ni iṣekuṣe, eru eke ni ao gbọn le e lori.

Iyemeji ko si ninu aisan Dokita Beckley, bẹni iyemeji ko si ninu iku rẹ pẹlu. Ekute Oko Awo ko de agbegbe rẹ. Dr. Macaulay to tọju rẹ jẹri si eyi, o si fi iwe ẹri ranṣẹ si ibi iṣẹ Ajiran (*Registry office*) ti nwọn ngba iwe oku ni Ẹhingbẹti.

Bi Dr. Macauley ti s'ori kọ n'ile rẹ lẹhinna to nkẹdun iku "arakọnrin" rẹ yi, bẹni o ngbọ ẹsẹ bata ka, ko, ka, ko ko lori pẹtẹsi rẹ. Nigbati o gbe oju s'oke, bẹni ọdọmọde kan, Dr. I. L. Oluwọle yo si i, o bere iru aisan ti pa Dr Beckley Dr. Macauley si sọ fun un.

O sọkalẹ lẹsẹkanna, ṣugbọn nibo ni a tun gburo Dr. Oluwọle lẹhinna pẹlu Dr. William S. Clarke Oyibo, bikoṣe ita Balogun nibiti oku Dr. Beckley simi si.

Bi Dokita Oyibo lo ni ki Dr. Oluwọle kalọ sibẹ ni o, tabi Oluwọle lo ni ki Oyibo sin on lọ si ibi ti ilẹ loju, awa ko mọ. Eyiti a mọ ni pe Dr. Oluwọle nikan lo lọ si ile Dr. Macauley lati wadi ọrọ nibẹ. Oluwọle nikan, ẹwẹ, ni a si gbọ pe o sọ fun ọkan ninu awọn aburo Dr. Beckley ni ita Balogun nigbati on pẹlu Dr. Oyibo lọ sibẹ pe, Dr. Macauley wipe on ko mọ iru aisan wo pato ~~lo~~ ṣe oniko iku Dr. Beckley gan. (*Dr. Macauley says he is not quite definite of the nature of illness to which Dr. Beckley succumbs.*)

Ati pe, nitorina, oku ologbe di lila.

Aburo Dr. Beckley yi bun nwọn ni suru pupọ lati duro de Dr. Macauley papa, ṣugbọn nwọn fi ake kọ'ri. Eyi ti a nwiyi pẹ ju, awọn lebira to tẹle wọn ti gbe oku Dr. Beckley ju sinu abapo tabi *Stretcher* kan lasanlasan; rẹ-rẹ, o di ile oku.

A ko rɔ pe oju oku ẹlẹwọn papa to p'okun so ni ọgba ẹwọn, le ri irikuri to ju eyiti oju oku Dr. Beckley ri ninu abapo lasanlasan ti nwọn gbe e si l'ọjọ na. O buru, o b'ogiri.

Bi eyi kukuru ko gbọn, kilo ṣe eyiti o gun. Oju ko ha ti Dr. I. Ladipọ Oluwọle lati ri iwọsi ti a fi lọ oku Dokita ẹlẹgbẹ rẹ bayi; ani, Dokita to ti gba oye janrẹrẹ nigbati on Ladipọ nwọ ṣokoto penpe lọ si Ṣukuru?

Nibo ni Ambulance Van ti a fi owo Ilu ra wa ti a ko le fi bọwọ fun oku ẹni nla ni ọna tirẹ bayi? Ọpa agbeleka, t'ẹhin l'o ju.

Ka fi ọrọ abapo silẹ, itumọ gbigbe ti nwọn gbe oku Dr. Beckley lọ si ile oku, laisọ ohunkohun fun Dr. Macauley to tọju rẹ.

Abuku nla ni eyi jẹ, ṣugbọn inu wa dun pupọ lati gbọ pe esi iwe Dr. Macauley si olori Dokita Ilu nipa ọrọ yi fun u ni itẹlọrun ati gafara to tu u ninu. Sibẹsibẹ, o yẹ ki awọn Dokita iyoku n'ilu gbarajọ pọ ton kọ iwe miran si Ijọba.

Igi gbọgbọrọ, ma gun mi loju, okere ni a ti nyẹra fun u.

Ọrọ ibinu ni eyi jẹ fun Ilu, ati ọrọ ibanujẹ fun gbogbo ẹbi Dr. Beckley, nitorina, ao m'ẹnu kuro nibẹ. Ṣugbọn ki a to ṣe bẹ ẹ, ao gba Dr. Isaac Ladipọ Oluwọle ni imọran Ifarabalẹ, *softly softly*. A ko le ba a ja to bi a ti fẹ gẹgẹ bi a ti le ba ara ode ja, nitori ọmọ wa ni ọwọ wa ni nwọn si bi i si.

Nję bi abiamo ba mba omo rẹ wi bayi, ko ha yẹ ki ẹniti ko ni iya, tabi ti iya rẹ wa ni ọna jijin rere fi ibawi na kọ ọgbọn? Nitorina, ẹnyin Dokita Oyibo olutọju Ilu, ẹsọ di ọwọ nyin o. A ko fẹ ki ẹnikẹni ninu nyin ri waya gba lojiji lati ilu Oyibo, ki o ma si ri aye duro mu fila ko to lọ.

Lakotan, a ki gbogbo ẹbi ologbe Dr. E. O Beckely nile, l'oko Ẹku ọfọ ajalu. Gbogbo nkan aiye, af'ọwọba-fi-silẹ. Asan ninu asan, bẹni oniwsu wi, gbogbo rẹ asan ni. Fāri owo ati owo, fuja ọla ati ọla, gbogbo rẹ asan ni.

*The boast of heraldry, the pomp of power, And all that beauty, all the wealth ere gave Await alike the inevitable hour The paths of glory lead but to the grave.*

Very sympathetically yours
ATARI AJANAKU.

---

## ATARI AJANAKU ATI RABIU B. JOSẸ.

Si Oni'we-irohin "Eko-Akete."

**Atagba,**

Ninu Eko Akete ti Satide keji ọhun, labẹ aṣaro lori rogbodiyan Oko-Awo, *Atari Ajanaku* wipe, awọn ẹlomiran ro pe boya Ọlọrun binu si adugbo na ni, nitori Afa Tijani to tilẹkun Mọṣalaṣi Jimọ ni ijelo, ati pe eyi le ri bẹ, o si le ma ri bẹ, awa-ma-ridi ni iṣẹ Ọlọrun. O dabi ẹnipe lati igbati wosika yi ti jade ni Rabiu ti dubulẹ aisan, nigbati o si daku ni Alaruba ijẹrin, bẹni Mọleka kan yọ si i loju ala, o si wi fun pe "Rabiu, dide, ki o si kede rẹ sinu Iwe-irohin *African Messenger*, ti ọjọ Alamisi pe, iwọ ti de Ọrun, iwọ si ti gbọ nibẹ pe, ọrọ ti *Atari Ajanaku* wipe on gbọ nipasẹ Oko-Awo ko ribẹ rara, awọn Gambari Olobi lo ko arun na wọ ibẹ."

Bawo ni iba ti dun to, bi o ṣe pe, a le ma ri Abiku tabi Ayun-Ọrun-bọ iru Rabiu Oloraye yi, ti yio ma fi opin si ariyan-jiyan to wa laiye, nitori nigbati araiye kan ba nṣiyemeji to si nro pe boya aṣiṣe ẹda le mu Aluba wọ ilu, ẹniti o ba sọ pato pe ko ri bẹ rara, kuro ni araiye, o ndi ara Ọrun.

Ṣugbọn nigbati ko nṣe Oko-Awo nikan ṣoṣo ni awọn Gambari Olobi ngbe, ti nwọn ngbe Ita Akanni, Agọ Hausa, Ọbalende ati adugbo miran kakiri ilu, ti a si fẹrẹ le wipe ojojumọ ni nwọn nlọ si *Custom* ni Ẹhingbẹti, ni Iddo ati ibomiran, boya akọwe-kọwura wa *Rabiu B. Jọsẹ* yio sọ itumọ Aluba Oko-Awo fun wa. Yio si tun jẹ ki a mọ bi ẹniti o jare to duro lori are rẹ ni ko jẹ ki ekuru tan, ti o ngbọn ọwọ rẹ silẹ ni o, tabi ẹniti a da l'ẹbi to tun nja ijakadi ati tun da nkan ru?

Ju gbogbo rẹ lọ, mo ki *Atari Ajanaku* pupọ fun wahala rẹ l'ọsan, l'oru, nitori ire ilu wa, nitori anfani Kiriyo, nitori alafia Imale, nitori ifọkanbalẹ Ko-kewu-ko-bere, ati nitori irẹpọ l'arin ilu ati Ijọba, ki Oluwa gbe ọwọ nyin si oke, ki o si ran nyin lọwọ o. Amin.

LAWANI B. SUBERU.

---

## A DUPẸ ỌJỌ.

Iya-afin Felicia Johnson ti No. 13, Ita Arọlọya pẹlu awọn aburo ati ẹbi rẹ dupẹ l'ọwọ awọn ọrẹ ati ojulumọ gidigidi fun ibakẹdun ti nwọn ṣe nipa iku aburo wọn Beatrice Latunji Cole ti o ṣẹlẹ ni ile Daddy Abọyade Cole ni ijọ kẹwa oṣu *August 1924.*

---


## T. A. Erinosho,

*Forwarding, Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent. Produce Merchant.*

*Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box, 242,
Lagos, Nigeria.

Ọgbẹni T. A. Ẹrinoṣo jẹ Ojulowo Oniṣowo. O nfi ọja ranṣẹ, o nta ọja, o si nra ọja, o jẹ Oniṣowo pataki ninu Ekurọ Epo, ati oriṣiriṣi Ọja miran. Ọgbẹni na si tun jẹ ẹniti o gba iwe ati ma ta Ilẹ, Ile tabi Oko.

Ẹ lọ fi Ọja nyin fun u ni:—
19, Opopo Tinubu,
Tabi ki ẹ kọwe si ni:—P.O. Box 242,
EKO.


---


AWỌN OKUN-ẸRỌ TI GRAMOPHONE FI NKỌRIN, ATI IGO IFI OMI GBIGBONA SI

(T'omi ko ni fi tutu gba wakati mẹrinlelogun).

Awọn Remi Macarthy *and Sons* ti nwọn ngbe 5, Taiwo *Street*, l'Eko ni awọn Okun-Ẹrọ ti *Gramophone* fi nkọrin lọwọ fun tita. Nwọn ṣẹṣẹ ri wọn gba lati Ilu Oyinbo, enia le lo wọn fun Ẹrọ *Gramophone* yala ti Gẹsi tabi ti Jamani. Wọn tun ni Igo ti a le fi omi gbigbona si gba wakati mẹrinlelogun. Owo pọ ọ ni wọn nta nkan wọnyi (Igo omi gbigbona fun tita wa) sure tete ki o wa ra tirẹ ki ẹran rẹ ma ba bi obukọ.

# LEVER STORES LTD.

## No. 1, LAGOS.

# OLOWO S'OKE D'ILẸ

A ni oriṣiriṣi ọja fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

A nta awọn ọja wa ni :—

3d. 6d. 9d. 1s.

A nṣi ilẹkun di agogo kan ọsọsan Thursday.

A si nti ilẹkun ni agogo meje alalẹ Satide.

## IKẸKẸRẸ NF'ỌRAN IKU Ṣ'ẸRIN.

Si *Editor Eko-Akete.*

Mo ṣi fila o.

O ti pẹ ti mo ti ngbero lati kọwe fi ki *Atari-Ajanaku* jagun a fidi alaṣeju bọ omi gbigbona fun onirunru ọrọ ti o nṣọ lọsọsẹ. Ọrọ ti o sọ sinu *Eko-Akete* ti ọtẹ yi lo mu ki o kuku ya kankan bayi. Ohun ti o mu mi pa owe ti o wa loke iwe yi ni pe :—

Ọpọlọpọ lo ti ka iwe na ni aka rẹrin ṣomiloju ninu awọn ti nwọn ti gbe arede. Ṣugbọn ọrọ yi ki nṣe ọrọ ẹrin arara bi a ba ronu jinlẹ.

Emi ti mo nkọ iwe yi, ohun ti oju mi nri nipa arede ti mo gbe nko le gbagbe lai. Ṣe bi ọna arede ti ri ni'lu Oyinbo ni *Atari Ajanaku* la silẹ fun wa yi ti olukuluku wa gbọ.

Gbogbo ohun ti mo ka ninu *Eko-Akete* lọtẹ yi mu ki ngbagbọ ati ki o si ye mi daju pe a nṣe afarawe awọn Oyinbo ni. Niwọn igbati o si ti le ri bẹ, o yẹ ki a fi arawe wọn jalẹ patapata. Iyẹn ni pe ki Tapa maṣe mu Gambari larede, ki Egun maṣe mu Yoruba, ki Adelamu maṣe mu Ilabiru. Ju gbogbo rẹ lọ bi ọkọ ẹnikan tabi aya rẹ ko ba pe l'õrun nijọkan ki a ma pe ẹjọ. Ṣugbọn lalai jẹ pe a ṣe nkan wọnyi, morope yẹyẹ la nmu ki iṣe arede. O dabi ẹnipe *Atari-Ajanaku* ti de ile mi tabi bi ẹnipe emi ni mo bẹ lọwẹ si awọn oniyẹyẹ nwọnyi ti nwọn ni awọn ngbe arede.

Ohun ti alarede nfi oju mi ri nko le sọ, ki Ọlọrun ki o ma ṣai ran *Atari Ajanaku* lọwọ nipa ọrọ yi ki olukuluku wa le mọ pe Jesu Kiristi ni Olugbala wa, ki iṣe awọn Oyinbo. Mo gbe arede, emi funrami ni mo nlọta ti mo nmu ọmọ l'ẹhin lọ ra nkan l'Ereko. Bi mo ba si pe Ẹlẹkọ tabi Onigari lati ba raja, arede a ma wo mi fokitoki bi ẹnipe mo ti ba oniyẹn sọrọ ni, alalikuwa bi mo ba pe e ki fẹ, bẹ kẹ on na nsọ ọpa ẹhin, njẹ bi ko ba si ti Oyinbo ti a nfarawe obinrin le ma rẹ enia jẹ bayi nitori Allah ? *Atari-Ajanaku* lo le gba wa lọwọ aṣa Oyinbo ti a fẹ fi ti ara wa si Oko Igba yi. O ma si san diẹ o nitori atunwa aiye mi nko ni ya ni'sọ alarede. Arede, Arede, Arede to, to, to fun u, o di aiye mi atunwa.

*Eko Akete,* ọwọ rẹ a roke o.

Emi ni tirẹ,

OJUMIRI.

## *This, That, and the Other.*

*By an old Crow.*

### SOFTLY! SOFTLY!

As things stand in Lagos to-day we think we have travelled far enough for the present on *spiritual* lines. What we want now is a proportional progress on lines political, educational, industrial etc., etc.

A Notice was placarded sometime ago by one who styled himself with a title not less than "The Prophet of Lagos." The other day we were reading something like this : "The Most Reverend Bishop of West Africa."

We do not question these good people whither they got their titles but we do say, at least : use them softly ! softly !

### GREATER LAGOS!

Mr. Olushola of Iperu—presumably The Editor of the late *Nigeria Labour Bulletin*—has contributed an interesting article on "Why is Lagos Overcrowded ?" in a local contemporary. He spoke of Lagos being the *City of Refuge* for those who have to face compulsory tribute tax in the interior, hence the congestion in Lagos. We do not believe that taxes even in the so-called *City of Refuge* are not compulsory. Rather, we are inclined to believe that the congestion may safely be attributed to her importance. A capital of British West Africa's wealthiest dependency Lagos must naturally receive a great influx of strangers in consequence of which, she must necessarilly be overcrowded.

Methinks in course of time Europeans may move *Ikoriward.* Natives towards Iru, Ido, Okobaba etc., etc. Now then, we shall have a *Greater Lagos* just as we have a *Greater London.* The next thing, we have *East-end* and *West-end* in London or at least we hear of them—good ! suitably, Okobaba could be our own *South-end* and Okun Alasia or thereabouts our *North-end !!!*

### COLOSSAL FIGURES.

Searching through the pages of an old Geography book for a different information we come across a statement that the earth as a body weights 5,425,092,500,000,000,000,000 tons.

What a colossal weight ! speaking of tons reminds us of our Cocoa Shippers here—they will no doubt imagine at once what these figures mean. But what really we wonder is whether or not there breaths a man who can put them into appropriate Yoruba words !!!

AN OLD CROW.

---

**Springs ! Springs !! Gramophone Springs !!!**

ALSO

**Isolated Bottles ; Vaccum Flasks.**

Messrs. Remi Macarthy & Sons, of 5, Taiwo Street, Lagos, has just received a consignment of Springs adapted either for English or German Gramophones. Also (Thermos Bottle) Vaccum Flasks to keep water hot for 24 hours. The Springs and Flasks are sold at very moderate prices. Come and pick yours ere the Stock exhausted. The Flasks are assorted sizes and bodies.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

---

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiogedẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa Pokun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (I'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ l'animọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

On si ni aşoju awọn ẹgbẹ Oyinbo onişowo to njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranşẹ orişi-rişi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ. Lọ ş'abere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ ni Şabu rẹ tabi ki o kọwe ranş si ki o fi sọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọbẹ P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

---

### Ẹ WA WO O.

Ọgbẹni E. A. Olemọh ti Ile Işẹ Oluwa, ni 73, Ọdunfa Street, (Anikantamọ) bẹrẹ işẹ agborun titunşe ti baba rẹ nisisiyi. Ojo ẹşe ti iwọ ati obinrin rẹ ma nsaba ju agborun nyin ti o ba bajẹ nu, Kai! Ọgbẹni kan mbẹ ni adugbo mi ti o mọ işẹ agborun nişişe lọpọlọpọ. Pọ lowo rẹ.

---

### ŞABU AJIŞEFINNI.

Gbakan-nşubu orişirişi Ọti *Beer* to jire wa fun tita ni Şabu Ibukun Oluwa, Şabu ti Mrs. A. Labinjọ ni No. 28, *Luther Street*, leti Mọşalaşi Olosun. Şarotu kẹkẹkẹ (*Cigarettes*) si nbẹ nibẹ bi tẹdi. Awọn *Lozenges* ati *Peppermint* lila, papa lakoko oworọ yi ko şe fọwọrọ sẹhin. Gbogbo-awọn ọja Şabu na lo nşẹju si ni, pe kami, kami, kami.

Ọrẹ, sure tete lọ ra tirẹ nibẹ.

Kai! afara ni'ja Ẹkun.

---

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neuerwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

---

**Ruby Plates! Ruby Plates!!**
**Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from:—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**



THE

# Pilsener Beer

*Lion Brand*

*Light & Sparkling*

Per Case

34s.



## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*


ILU ẸPẸ KO KERE L'AWO, ẸIYE O BA LO GE.

Ọgbẹni S. A. Ọ. Macaulay ti No. 88 l'Eko nibi ṣẹṣẹ ṣi Ile Egbogi to kẹriri kan si eti Ebute l'Ẹpẹ.

Ile Egbogi na ko jina si Ile-Ọja awọn Oyinbo Oniṣowo John Holt.

Ọgbẹni yi ni Ajaloleru Egbogi ni Ṣabu na, eyiti ki fojo arunkarun ba'lẹ gẹrrẹ ti a ba ti lo wọn.

Ẹ waidan a wo: bẹ lẹ o ba

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn


## B. A. ỌLA SILVA,

**Certificated Typewriter Mechanic**

*5 years Mechanical experience Marine Work Shops.*

Undertakes Repairs of Typewriters, &c., at moderate charges.

*Business Place:*

30, DOHERTY STREET, LAGOS.

**A Trial Solicited**



## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

88, BROAD STREET.

Wabiwosi orişirişi Egbogi lo şęşę de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orişirişi, ogun Ẹda, ogun arun aşiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mñ to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wonyi wo nibi ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.